# AIMOORE AWỌN ỌMỌ ISRAẸLI

## Numeri 11:1-35; Orin Dafidi 78:17-41

### ẸKỌ 99 – FUN AWỌN AGBA

**AKỌSORI: "Iwọ fun wọn li ẹmi rere rẹ pẹlu lati kọ́ wọn, iwọ kò si gba manna rẹ kuro li ẹnu wọn, iwọ si fun wọn li omi fun ọrungbẹ wọn" (Nehemiah 9:20).**

**I Iráhùn Awọn Ọmọ Israẹli**

1. A ko sọ fun ni idi iráhùn ti o mu idajọ ojiji ba awọn eniyan naa, Numeri 11:1; Orin Dafidi 78:17; Filippi 2:14; Owe 19:3; Juda 16; Heberu 12:29; 13:5; Deuteronomi 32:22
2. Lẹẹkan si i, Mose tun fi ara rẹ̀ hàn gẹgẹ bi oloootọ onilaja nipa gbigbadura fun awọn eniyan naa, Numeri 11:2, 3
3. Irahùn miiran bẹrẹ lati ọdọ awọn adalu ọpọ eniyan ti o mu ki wọn korira ounjẹ Ọlọrun, ki wọn si ṣe ifẹkufẹ ounjẹ Egipti, Numeri 11:4-9; Orin Dafidi 78:18-25; Numeri 21:5; Orin Dafidi 74:14; 106:13-15; 1 Kọrinti 10:1-11; 15:33; 2 Kọrinti 6:14; Orin Dafidi 1:1; Owe 4:14; Johannu 6:31-35

**II Ẹbẹ Mose, Idahun ati Itọni Ọlọrun**

4. Igbe irahùn wọn de Ọrun o si mu ki Ọlọrun binu si awọn Ọmọ Israẹli, Numeri 11:10; Orin Dafidi 106:25, 26; Numeri 14:22, 23; Deuteronomi 9:22; Heberu 3:16-19
5. Adura Mose fi han pe o ni imọ nipa ailagbara ti rẹ̀ ati bi o ti ṣe danindanin pe ki Ọlọrun ru ẹru awọn eniyan ọlọtẹ naa, Numeri 11:11-15; 1 Awọn Ọba 19:4-8; 2 Kronika 20:12
6. A sọ fun Mose ki ó yan aadọrin eniyan ti a ti danwo, ti wọn si yẹ, awọn ti kò ṣai ní iriri, lati maa ràn án lọwọ, Numeri 11:16, 17; 1 Timoteu 3:8-10
7. Ọlọrun rán Mose si awọn Ọmọ Israẹli, Mose si pada jiṣẹ wọn fun Ọlọrun, ó sọ ibeere nlanla ti wọ́n n beere lọwọ Ọlọrun, Numeri 11:18-23
8. A fi ororo yan aadọrun alagba fun iṣẹ wọn, eyi ti i ṣe apẹẹrẹ fifi agbara Ẹmi Mimọ wọ ni, eyi ti yoo mu ki awọn Onigbagbọ le ni agbara fun sisin lẹyin ikú ati igoke-re-Ọrun Kristi, Numeri 11:24-30

**III Abayọrisi Iráhùn Awọn Ọmọ Israẹli**

9. Ọlọrun rán aparo lọna àwámáridi lati tẹ́ ifẹ ọkan awọn eniyan naa lọrun, Numeri 11:31, 32; Orin Dafidi 78:25-29; 105:40, 42
10. Ibeere buburu naa ti kò duro lori ifẹ Ọlọrun fa ibi pupọ wá sori wọn, Numeri 11:33-35; Orin Dafidi 78:30-33; 106:15; Isaiah 10:15, 16; Matteu 6:10; 26:39; Johannu 7:17; 1 Johannu 2:17; 5:14, 15
11. Ironupiwada wọn ninu wahala ki i ṣe iru eyi ti inu Ọlọrun dùn si, Orin Dafidi 78:34-37, 40, 41; 95:8-11; 2 Kronika 7:14; Isaiah 55:7; Joẹli 2:13; Orin Dafidi 66:13-15
12. Ọlọrun ranti pe ẹlẹran-ara lasan ni wọn, O dari irekọja wọn jì wọn, ko si run wọn ninu ẹ̀ṣẹ wọn, Orin Dafidi 78:38, 39; Isaiah 40:6-8; 1 Peteru 1:24

## ALAYE

**Iráhùn di Ẹ̀ṣẹ̀**

Ọrọ diẹ ti o bẹrẹ ẹkọ wa fẹrẹ le mu arẹ ba ọkan nigba ti a ba kọkọ bẹrẹ si ka a, ṣugbọn nigba ti a ba ronu jinlẹ le e lori, yoo mu iṣiri ba ni bi a ba fi ọkan ṣiro ohun ti o ṣẹlẹ ninu ati ni ayika ibudo awọn Ọmọ Israẹli ni gẹrẹ ti wọn bẹrẹ irin-ajo wọn yii. "Awọn enia na nṣe irahùn" si Ọlọrun ati awọn iranṣẹ Rẹ̀ nigba pupọ -- ani nigba pupọ ju – titi irahùn wọn fi fẹrẹ di ẹ̀ṣẹ̀. Ṣugbọn nigba yii, idajọ Ọlọrun sọkalẹ si wọn lori kiakia bi wọn ti bẹrẹ si ṣe irahùn aigbagbọ wọn. "Iná OLUWA si ràn ninu wọn" lati fi iṣina iwa ikoro wọn hàn wọn.

Mose tun sá tọ Ọlọrun lọ nitori awọn eniyan yii, bi o ti i i maa ṣe nigba pupọ tẹlẹ ri. Ọlọrun gbọ́ adura rẹ̀, iná ti n jonirun naa si rẹlẹ, a si dá ọpọlọpọ ẹmi sí ṣugbọn eyi ko fi opin si irahun wọn, bẹẹ ni ko si mu ki ọkàn awọn eniyan naa yipada si Ọlọrun patapata, bi a ti ro pe o yẹ ki o ri. Awọn adalu ọpọ eniyan ti ba wọn jade lati Egipti wa, awọn wọnyi ko si fi tọkantọkan tẹle Ọlọrun patapata, bẹẹ ni wọn ko si bu ọla fun Un bi o ti tọ ati bi o yẹ. Awọn adalu ọpọ eniyan yii "ṣe ifẹkufẹ," apẹẹrẹ buburu wọn si mu ki awọn Ọmọ Israẹli rahùn pẹlu ẹkun si Ọlọrun nitori ounjẹ ti a fun wọn lati jẹ.

**Ewu Ti O Wà ninu Kikó Ẹgbẹ́ Buburu**

Onigbagbọ ni lati fara balẹ yan ẹgbẹ́ ati ọgba rẹ̀. O n gbe inu ayé ẹ̀ṣẹ, o n ba awọn olugbe inu rẹ̀ ṣiṣẹ, titi de àyè kan o si n gbe laaarin awọn alaiwa-bi-Ọlọrun. Ṣugbọn Onigbagbọ ni lati mọ ewu ti o wa ninu fifi ara mọ ẹnikẹni timọtimọ ninu awọn "adalú ọ̀pọ enia," ki oun ki o ma ba fi ara kó ẹ̀ṣẹ awọn eniyan yii tabi ki o fara mọ wọn ju bi o ti

yẹ lọ dipo ti i ba fi wà laaarin awọn ọmọ Ọlọrun. Ninu ẹkọ yii awọn Ọmọ Israẹli n beere fun ounjẹ Egipti dipo ounjẹ Ọrun!

Kikùn awọn adalu ọpọ eniyan mu ki awọn Ọmọ Israẹli gbagbe iyà ti wọn jẹ ni Egipti. Wọn ranti awọn akọtun ounjẹ ti o wa nibẹ ṣugbọn wọn gbagbe ìṣẹ́ ti o bá wọn lọhun. Ọlọrun ti pese fun gbogbo aini wọn ni kikún ninu aginju. Ọlọrun kò kuna lati fun wọn ni manna, gẹgẹ bi O ti ṣeleri. O fun wọn ni ẹran jẹ niwọn bi o ti tọ ni oju Rẹ (Orin Dafidi 74:14). O mu iṣan omi jade lati inu apata wá, O si sọ omi kikoro di didùn fun ilò wọn. Iráhun wọn ki i ṣe ti awọn ẹni ti ebi n pa ti ounjẹ oojọ ko si fun. Irahun wọn jẹ ti imisi ara, aileko-ara-ẹni ni ijanu, aini igbagbọ ninu Ọlọrun Ọrun on aye, ati aimoore fun gbogbo nnkan ti Ọlọrun Abrahamu ti ṣe fun wọn.

Ko si ẹ̀ṣẹ ti o tabuku si ọla Ọlọrun bi aigbagbọ. Aigbagbọ yii jinlẹ lọkan awọn ẹlomiran to bẹẹ ti o fi jẹ pe bi wọn tilẹ ri iṣẹ iyanu nla nla ti Ọlọrun ṣe, sibẹ wọn o maa ṣiyemeji pe O le pese fun aini wọn ti o kere ju lọ. Alaigbagbọ ko jẹ gba lati jẹwọ pe Ọlọrun fẹran eniyan to bi Onigbagbọ ti mọ pe Ọlọrun fẹran wa. Eniyan ni lati maa yẹ ọkàn rẹ wò nigbakuugba lati ri i daju pe ọta ẹmi ko funrugbin ẹṣẹ buburu yii sibẹ.

Awọn Ọmọ Israẹli jẹ orilẹ-ede kan ti Ọlọrun ṣe oju rere si ju gbogbo orilẹ-ede lọ, ṣugbọn a fẹrẹ le sọ pe ko si ẹni ti o jẹ́ alaimoore bi awọn eniyan yii -- ṣugbọn nigba ti awa paapaa ba yẹ ọkàn ara wa wò a o ri i pe oore-ọfẹ irapada Ọlọrun nikan ni o mu ki a sàn ju wọn lọ. Manna sọkalẹ lati ọrun wa fun wọn, ṣugbọn kikùn ati irahùn ni wọn fi san án pada. Odo omi iye tú jade fun wọn lati inu apata wa, sibẹ ẹkun rẹrẹ iwa buburu ni wọn fi san ẹsan rẹ̀. Ọlọrun ko fi wọn silẹ nigba kan ri, O pese fun wọn ni ọna iyanu pupọ, ṣugbọn wọn kò ni igbagbọ pe O lagbara lati pese ẹran fun wọn lati jẹ.

Ounjẹ Ọrun ti sú wọn to bẹẹ ti wọn fi n fẹ ohun miiran – ohun ti awọn ati Ọlọrun paapaa mọ pe ko ṣe danindanin fun wọn lati mú wọn wà làyè. Nigba ti wọn kùn nitori omi ni Massa, a le foju wò pe o nidii ti wọn fi ṣe bẹẹ nitori wọn n beere ohun ti o ṣe pataki lati mú wọn wa laaye. Ẹṣẹ wọn nigba naa ni pe wọn kùn dipo ti wọn i ba fi gbadura! Ṣugbọn nihin yii wọn n fẹ ohun ti ko ni laari. Ohun ibi ni lati ṣai gbẹkẹ le Ọlọrun, nigba ti oye kukuru wa bi ẹda ba n fi ye ni pe aini pataki ni o de ba wa, ṣugbọn ohun ti o buru jai ni pe ki o jẹ pe iwa ojukokoro fun ohun asán ni ọkan naa n wára pàpà fún.

Ọkàn ti ko ni itẹlọrun a maa ro pe on yoo ni itura ninu ohun ti a fi du u; ṣugbọn iru ọkàn bẹẹ ki i ni itẹlorun nigba ti ọwọ rẹ ba tẹ ohun ti o n fẹ. Ṣugbọn igbagbọ ki irahun kàkà bẹẹ a maa dupẹ nigba gbogbo fun ohun gbogbo. I ba ṣe pe awọn Ọmọ Israẹli sun mọ Ọlọrun dipo ti wọn fi fara mọ awọn adalu ọpọ eniyan, wọn i ba ri itura ati adun ọtun ninu manna ti Ọlọrun n pese fun wọn bi wọn ti n jẹ ẹ lọjọọjọ. Orin iyin ni wọn i ba kọ dipo ohun aro, irahun ati aroye. Ẹ jẹ ki a fi ọpẹ fun Ọlọrun fun awọn ibukun ti a n ri gba dipo ki a maa kùn nitori ohun ti a ro pe o jẹ́ aini wa.

### Adura Ilaja

Mose mọ aṣiri aṣeyọri ninu iṣẹ Ọlọrun, eyi yii ni nipa adura ilaja. O mọ pe irahun, ifẹkufẹ ati ọtẹ ti i ṣe ọṣọ ọkan ẹṣẹ ki i ṣe ohun ti a le ṣakoso a fi bi Ọlọrun tikara Rẹ̀ ba jẹ Alakoso awọn eniyan yii. O mọ pé oun ko ni agbara lati ṣakoso awọn eniyan wọnyii ti wọn ni ọkàn lati pada si Egipti nigba gbogbo.

A le kọ́ ẹkọ nla nla nipa iwa Mose ni akoko yii. Awọn miiran yàn lati dá a lẹbi fun ọna ti o gba gbadura ni akoko yii. Wọn n sọ fun ni pe o yẹ ki Mose tikara rẹ̀ jẹ "òpó" ti ko gbọdọ ṣubu labẹ ẹru ti a gbe ru u bi o ti wu ki o ri. Ṣugbọn eniyan ẹlẹran-ara ni Mose, bi o tilẹ jẹ pe o jẹ apẹẹrẹ Alagbawi wa Nla ti o n bọ wá. Ẹru awọn eniyan wọnyii pọ ju fun Mose tabi ẹnikẹni ti o wu ki o jẹ, lati nikan rù. O mọ pe oun ko lagbara lati le ṣe eyi. Ki i ṣe ohun ti o buru bi a ba ri i pe alaipe ni a jẹ ninu agbara ti wa lati ṣe ohun ti Ọlọrun fẹ ki a ṣe. Ohun ti o ni iyin ni fun ẹnikẹni lati mọ pe tito ati agbara oun wà ninu Ọlọrun, ati pe oun ni lati gbe ara le Ọlọrun; bi bẹẹ kọ oun yoo ṣubu labẹ ẹru naa. Iranlọwọ wa ko si ninu ipa ti wa. Ninu Ọlọrun nikan ni iranwọ wà.

Ẹni kan ṣoṣo ni O le ru ẹbi ẹṣẹ ọmọ eniyan, Oun ki i si i ṣe eniyan lasan. Jesu Kristi Oluwa ni. Nipa ijẹwọ ọkunrin nla yi, ani Mose, pe alailagbara ni oun jẹ, a tun le ri ẹkọ kọ nipa bi iṣẹ ilaja Ẹni ti Oun tikara Rẹ "fi ara rẹ̀ rù ẹ̀ṣẹ wa lori igi" ti tobi to ki a si mọ pe a ni lati ni iranlọwọ Ọlọrun nigba gbogbo.

### Ileri Ọlọrun

Idahun Ọlọrun tó lati tan gbogbo aini ati ẹbẹ Mose ati awọn eniyan naa. A yan aadọrin eniyan laarin awọn alagba lati maa ran Mose lọwọ. Ọlọrun yoo si fi aṣẹ ati ifororoyan Rẹ̀ fun wọn fun iṣẹ ti o wa niwaju wọn. A o fi ibeere awọn eniyan wọnyii fun wọn, wọn o si ni anfaani lati jẹ ẹran ti ọkan wọn ti n fẹ ni ajẹyo. Ileri ti o tobi ni eyi jẹ, imuṣẹ rẹ si kọja ohun ti ẹnikẹni wọn le ro tabi ki o woye.

Nigba ti Mose, ẹni ti ọran awọn eniyan wọnyii ti sú, bẹrẹ si i ṣiro ohun ti yoo ṣẹlẹ ki a to le mu ileri yii ṣẹ, Ọlọrun ba a wi nipa bibeere lọwọ rẹ bi ọwọ Oluwa kuru, tabi boya Oun ko ni agbara to lati pese fun ohun ti awọn eniyan yii n fẹ́. Bi a ba sọ pe ọwọ eniyan kuru, ninu ede wọn, awọn Heberu gba pe oluwa rẹ yarọ tabi ko lagbara. Awọn

Larubawa ati awọn ara Persia ti ode-oni a maa lo ede bẹẹ -- **ọwọ gígùn** duro fun **agbára, ọwọ kukuru** si duro fun **ailera.**

Ọlọrun fun Mose laṣẹ lati yan aadọrin ọkunrin ninu awọn agba Israẹli ki o si mu wọn wa sibi Agọ. Mose nikan ni eniyan ti o ni ẹtọ lati mọ̀ bi wọn ba yẹ. Ọlọrun a maa fun awọn alakoso ti O ba yan ni ọgbọ́n fun iṣẹ kọọkan ti O ba yan fun wọn – nigba ni ati nisisiyii pẹlu! (Ka 1 Awọn Ọba 3:4-14). Ki i ṣe awọn eniyan ni o yan awọn ọkunrin wọnyii ṣugbọn Ọlọrun ni o yàn wọn si àyè naa, nipasẹ Mose, Ọlọrun funrara Rẹ si kọ́ wọn. Ko si si ẹni ti o lẹtọọ lati yan awọn oṣiṣẹ ti yoo di ipò pataki mu ninu iṣẹ Ọlọrun bi ko ṣe alakoso tabi alabojuto ti Ọlọrun gbe iṣẹ Rẹ̀ le lọwọ. Ọlọrun yoo maa tọ ọ bi o ti n sin In ti o si n tọju agbo ijọ Rẹ. Gẹgẹ bi oluṣọ-agutan ati alakoso rere, Mose ṣe bi o ti ri pe yoo tẹ́ Ọlọrun lọrun, o si yan awọn eniyan ti o mọ̀ ti o si ri pe Ọlọrun fẹ ki oun yàn. Alakoso tootọ ni oun jẹ́, o jẹ oloootọ si Ọlọrun ati si Israẹli pẹlu.

Awọn meji ninu awọn ti a yan kò le fara han nibi Agọ ajọ fun idi ti o yé awọn ti igba ni, ṣugbọn ti ko di mimọ̀ fun wa. Ṣugbọn eyi ko mu ki awọn meji wọnyi má ni iru agbara ati ifororoyan ti awọn mejidinlaadọrin iyoku ti o duro niwaju Oluwa nibi Agọ ajọ ri gbà. Ni gbogbo igba ati akoko ni Ọlọrun ti yan awọn eniyan Rẹ̀, ti O si ti n fi agbara fun wọn, pẹlu ọtọọtọ aṣayan ẹbun, agbara ati Ẹmi Rẹ̀ lati le ṣe iṣẹ Rẹ̀. Ni igba Majẹmu Laelae, agbara Ẹmi yii a maa ba le wọn fun iṣẹ tabi idi pataki kan, a ko si fi fun wọn lati maa ba wọn gbe gẹgẹ bi i ti maa ba ijọ ti ode oni gbe lati igba ti a ti kọ tu U jade ni Ọjọ Pẹntekọsti. Ifarahan Ẹmi Ọlọrun yii ni ibẹrẹ igbesi-aye awọn Ọmọ Israẹli ni a le pe ni apẹẹrẹ itujade ti o n bọ wá, ti ki i ṣe awọn aṣayan eniyan diẹ ni yoo ri ẹkun rẹrẹ rẹ̀ gba, ṣugbọn gbogbo awọn wọnni pẹlu ti o le ṣe ohun ti Ọlọrun beere lọwọ wọn, ti wọn si gbadura "pẹlu ọkan kan," lẹyin ti a ti sọ wọn di mimọ́ patapata (Joẹli 2:21-32; Iṣe Awọn Aposteli 2:1-21).

**Ere Ifẹkufẹ ati Iwọra**

Ni aipẹ jọjọ, afẹfẹ kan ti ọdọ Oluwa wá ti o mú aparo wá si ibudo awọn Ọmọ Israẹli. Ọlọrun rán aparo, ounjẹ aladun, nigba ti o ṣe pe iná ati sulfuri ni o yẹ ki O rán! Ṣugbọn bi o ti jẹ pe wọn gbe irahun wọn kalẹ lọna ti o sẹ́ ipá ati agbara Ọlọrun lati le tẹ́ wọn lọrun, nitori naa Ọlọrun kọkọ fi agbara Rẹ̀ han fun wọn, lati fi bi aigbagbọ wọn ti buru to hàn fun wọn ati fun awa naa pẹlu. Lẹyin naa O rán ijiya ti o tọ́.

Igbadun wọn naa ko pẹ. Nigba ti ẹran naa wà ni ẹnu wọn sibẹ, ki wọn tilẹ to jẹ ẹ, ibinu Ọlọrun sọkalẹ si wọn lori a si fi arun nla kọlu wọn. Isinku ọpọlọpọ eniyan ni o gbẹyin ajẹki mimu ati ariya wọn.

Wọn ko ni itẹlorun pẹlu ipese ti o to fun oojọ, gẹgẹ bi Ọlọrun ti fẹ ki a ni itẹlọrun, ṣugbọn ninu iwára pàpà ati ojukokoro wọn, wọn ko ọpọlọpọ aparo jọ, wọn si sa wọn silẹ ki wọn le gbẹ. Lai si aniani, idi ti wọn fi ṣe bẹẹ ni lati pese fun ọjọ ọla. Nigba ti wọn ko ri ounjẹ jẹ, wọn kun, Ọlọrun si fun wọn ni manna lojoojumọ. Wọn tun kun nitori manna, Ọlọrun si tun pese ààyè aparo iyanu fun wọn lọpọlọpọ, ṣugbọn a ko ri i ka pe wọn tilẹ dupẹ lọwọ Ọlọrun lẹẹkan ṣoṣo.

Wọn tilẹ ti ṣiyemeji pe boya Ọlọrun ko fẹ fun wọn ni ẹran lati jẹ nigba ti wọn n rahun nipa ohun ti o de ba wọn, Sibẹ wọn ko tun ni igbẹkẹle si I nitori iṣe wọn fi han pe wọn ko gbagbọ pe Oun ni O pese ẹran naa fun wọn lati jẹ, wọn gba pe aparo ti wọn ri jẹ dédé wá ni. Nipa iwa iwọra ati ajẹki wọn, wọn fi han pe wọn ka eyi si anfaani ti wọn ko gbọdọ fi jafara nigba ti o wà ni arọwọto wọn, nitori o ṣe e ṣe ki iru bẹẹ má tun ṣẹlẹ mọ lae. Awọn kan, awọn oluka Bibeli gba pe ẹni kọọkan kó tó ọgọrin oṣuwọn.

Nipa gbogbo ohun ti o fara han, o dabi ẹni pe àrun aigbagbọ awọn eniyan wọnyii ti di baraku ati eyi ti ko ṣe e mu kuro. Iṣẹ iyanu, yala ti idajọ tabi ti ọwọ́ aanu ko mu iyipada ba ọkan aigbagbọ wọn. Ohun iyanu ni o jẹ fun wọn nigba ti wọn ba ri ninà apa Ọlọrun ti o dide fun iranlọwọ wọn, ṣugbọn eyi ko yi wọn lọkan pada lati gbagbọ! Ẹni kan ti wi bẹẹ lootọ pe tọmọ tìyá ni aigbagbọ ati ẹṣẹ jẹ́. Ẹṣẹ ti gbadun mọ awọn Ọmọ Israẹli wọn ko si fẹ kọ ọ silẹ, nitori naa wọn n tẹ siwaju ninu aigbagbọ wọn ki wọn má ba kọ ẹṣẹ silẹ. Ẹ jẹ ki a gbadura si Ọlọrun ki O fun wa ni ọkàn ti o n ṣafẹri iwa mimọ́ ati igbagbọ ti o duro ṣinṣin ninu Ọrọ Mimọ́ Rẹ̀.

Onisaamu sọ fun ni pe wọn ni ifẹ diẹ lati wa Ọlọrun wọn si fi ẹnu lasan beere ifẹ Rẹ̀, ṣugbọn ete wọn sọrọ ẹtan, adura wọn si jẹ ipọnni lasan. Ọkàn wọn ko ṣe deedee pẹlu Ọlọrun. Ifẹ rẹ̀ ko leke ninu ọkan wọn. Wọn ko ni itara lati ṣe ifẹ Rẹ̀ ati lati jẹ ki ifẹ Rẹ ṣẹ ninu wọn. Wọn fẹ lati tọ ipa ọna ara wọn. Ṣugbọn onisuuru ati onipamọra ni Ọlọrun. O fi aanu ba wọn lò, O ranti pe erupẹ ṣá ni wọn, wọn si dabi koriko ati itanna eweko igbẹ ti o n kọja lọ.

A! aanu Ọlọrun ti pọ to! O wà "lati aiyeraiye" (Orin Dafidi 103:17); "anu rẹ̀ duro lailai" (Orin Dafidi 106:1); "o tobi ju ọrun lọ" (Orin Dafidi 108:4); "o gba ilẹ aiye kan" (Orin Dafidi 119:64).

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ṣe ti iná-idajọ Ọlọrun ràn ni ibudo Israẹli?
2. Ki ni Mose ṣe nigba ti iná yii sọkalẹ?

3. Lati ọdọ ta ni kikùn nipa manna gbé bẹrẹ?
4. Ẹkọ wo ni a ri kọ́ ninu ori iwe yii nipa yiyan awọn ọrẹ ati ẹlẹgbẹ wa?
5. Ki ni awọn Ọmọ Israẹli fẹ́ dipo manna?
6. Ọna wo ni a le wi pe wọn gba dẹṣẹ nipa fifẹ ohun miiran ti o yatọ si manna?
7. Eniyan Ọlọrun miiran wo ni o gba adura ti o fara jọ adura ti Mose gbà, nigba ti Oun naa wà ninu iṣoro?
8. Njẹ Ọlọrun gbọ adura Mose? Ki ni esi ti a fi fun un bi O ba gbọ́?
9. Ki ni Ọlọrun ṣe ni idahun si irahùn awọn Ọmọ Israẹli?
10. Iwa Ọlọrun wo ni o fara han ju lọ ninu gbogbo ilosi Rẹ̀ pẹlu awọn Ọmọ Israẹli?